## OWUYẸ.

Ọyẹ tun ṣẹṣẹ de b' ẹnipe ko ti i ja rara ni ọdunni. Mimu na ko l' ẹgbẹ; Efufu lẹlẹ rẹ si pọ. Akoko yi ni ẹsin ni ina jo ni ilu ki mẹrin pẹlu ofo enia pupọ. Nitorina, a kesi awọn ẹniti nda ina pe ki nwọn ṣe pẹlẹpẹlẹ, ki nwọn ma si fi ina jafara ni sáà yi.

## ADUKẸ ỌMỌ SANTOS.

A ki Iyafin Q. B. Santos "Ku Iyaiẹmọ" ti aręmọbirin rẹ Aduke ti o fẹ sin ni iyawo fun ọkọ rẹ ni ọjọ kẹfẹlogun oṣu yi. A si ki gbogbo awọn ẹbi, E ku imura nã.

Ki Baba m' ọjọ ro o.

## ṢỌPỌNA DE IKIRE.

Anu ṣeni nigbati a gbọ pe arun Ṣọpọna de Ikire, o si mba ọpọlọpọ enia ja nibẹ.

Tẹlẹtẹlẹ. Ikire jẹ orita awọn ero Ile-Ifẹ, Ilesa, Okeigbo, Ondo, Ekiti, ati awọn ilu miran: o si tun jẹ ọkan ninu awọn ilu ti o ni Xòkó ati Ekuro; ogunlọgọ awọn oniṣowo ni nwọ ibẹ ni ojojumọ pẹlu mọto oniruru lati Ibadan, Il... ati awọn ilu miran.

A o dupẹ lọwọ Ijọba bi nwọn ba le tete mojuto arun yi, nitori ewu pāpa ni i fun Ibadan ati ilu ti o yi wọn ka.

## NEWS AND NOTES.

The Mass Meeting convened at Ẹrẹ Court by the Hon. E. H. Oke, M.L.C., came off successfully. A Working Committee representing every section of the community was elected and empowered to devise ways and means to welcome the Prince on his arrival.

To avoid disturbing the Court and Tribute Officials, a meeting of the Working Committee was arranged to take place in the Grammar School Hall, on Monday the 12th instant

## MISSING.

Bon voyage to His Honour the Lt. Governor Southern Provinces Lt. Colonel H. C Moorhouse C.M.G., D.S.O., who is proceeding to England on furlough.

Mr. E. A. Williams the Train Guard at Minna who took ill while spending part of his leave at Lagos, has since recovered. The gentleman travelled by Kano train to resume his duty on the 12th instant.

Ọko a re fi o! Ọmọ Jọjọlọla Olubi Opo ọmọ Aragba

## OUR FUTURE KING'S VISIT TO NIGERIA.

**We are indeed very glad to see many publications in the Nigeria Local news papers about our future King's Visit to Nigeria in April this year.**

**All best suggested methods or plans and arrangements to welcome him wholeheartelly will be received by us, with most cheerful and enthusiastic alacrity.**

**It shall be most pleasing and gratifying if his arrival will be the first to bring us the knowledge of an aeroplane in Nigeria.**

**As we learnt, he will visit Kano and some other important places; how tremendously nice a look it shall be if our Popular Prince flies along from Lagos to Kano & comes down at all important places or stations of visit, as may be arranged, thus markingthis greatest event of its own with a peculiarity of its kind.**

**We Subjects pray with one accord,**
**Where British rules prevail!**
**Preserve our Emperor King O Lord**
**And bless the Prince of Wales**

**Gwada, 1925. EJOFO.**

A young boy named Daniel Oyetunji Akinola about 12 years of age; Dark complexioned with Gombo face-marks.

Whoever finds him should please communicate with the Police, Akọda or the boy's father Mr. Emanuel Akinọla, Iwo station.

## EJIGBO.

### Iku Gbigbona.

Anu nla seni lati fi iru irohin bubu-ru bi iru eyi ti a ri ni ijọ keje oṣu yi bẹrẹ Irohin wa ti ọdunni.

Nigbati o di ijọ keje oṣu yi ni awọn obirin bi mẹdogun lọ si oko lati lọ ṣe igi ti wọn yio fi fun Oniyawo gẹgẹbi àṣà wa. Nigbati awọn enia wọnyi ṣe igi nā tan l'oko, nwọn si gberu ara wọn; nwọn dori kọ ile; bẹ ẹ ni ẹnikan fi ina si igbẹ: bi igbẹ yi ti njo bọ, bẹni awọn obinrin wọnyi bẹrẹ si sare pẹlu gbogbo agbara wọn -(gẹgẹbi a ti mọ pe, o sa ni ibiti obinrin le sare mọ.) bẹni ina ba pa obinrin mẹfa, ọmọ kekere ṣe ikeje wọn. Ki Oluwa ba wa tu awọn enia wọn ninu, ki O si fi ọran mọ bẹ ẹ fun wọn.

A dupẹ lọwọ Ajẹlẹ Oṣogbo ti o o ba wa fi opin si ọran fifi oku enia se Atan laisin i ni ilu Ọla, gẹgẹbi ati ri i ka ninu "Yoruba News" ti oṣu December number 49.) A ri i pe Oluwa tikalarẹ li o mu opin nā ya kiakia bayi:—

Awọn ọmọde onigbagbọ lọ dẹ isa Okete (big rat), wọn si ba okete meji ninu iho nā: wọn pa ọkan ninu wọn ọkan yoku si sa lọ si ile ti nwọn gbe ṣe atan oku enia si; ṣugbọn okete wọ awọn ọmọde wọnyi loju tobẹ ẹ ti nwọn nfi igi ru iho ti okete kan yoku sa wọ, nigbati awọn alaigbagbọ ri wọn nibẹ: ile ti nwọn bọ si, ṣile meje (7/-) ni nwọn lọ mu, wọn si kọri si Kotu Ejigbo.

Ṣugbọn ẹjọ yi ko le pari ni Kotu Ejigbo, nitoripe awọn onigbagbọ ṣe ori re ni ọjọ nā gān ni Ajẹlẹ Agba (Senior-Resident) wọ Ejigbo, ẹniti o sọ pe Ajẹlẹ ti o wa ni Oṣogbo yio wa wá idi ẹjọ nā lati mọ ẹlẹbi ati alare.

Ajẹlẹ nā wa de si Ogbomọṣọ ni ijọ kẹfa oṣu Jan, 1925, nigbati o di ijọ keje ti nwọn yio bẹrẹ si ma wa idi ọran yi wo nibẹ ni nwọn gbe ba ọran ti oku enia fifi ṣe Atan laisin pade.

Bayi ni Ajẹlẹ ba sọ fun wọn pe wọn ko gbọdọ tun se bẹ ẹ mọ lailai, ati pe ki nwọn ki o yara sare lọ sile lati sin eyi ti mbẹ nilẹ.

A dupẹ lọwọ Ajẹlẹ o! ỌMỌBILẸ.

---

## OWO

Oniwe Irohin Ilẹ Yoruba,

Mo ki nyin pupọ, ẹ ku iṣẹ ati ilọsiwaju ilẹ wa. Ki Ọlọrun ran alafia rẹ si ori ilẹ wa o.

Mo yọ lati sọ inkan diẹ fun ẹnyin Oniwe irohin Ilẹ Yoruba, nipa ilọsiwaju ilu Ọwọ. Iyatọ nlanla li o wa ni Igboro Ọwọ nisisiyi bi ati iwọn ọdun meji sẹhin. Igboro mọ si i nwọn kọ ile si i, ile pamu dā lā, gbogbo awọn ijoye ni nwọn ngbiyanju ati kọ ile pānu; ati pẹlu gbogbo awọn ni nsowo Ekuro; awọn Ijoye meji ni awọn mura ju: eyi ni Oloye Sasẹrẹ, o ti kọ idaji ile baba rẹ ni pānu, o si mu ọpọlọpọ ilaju wa pẹlu, ati iṣẹ ti Oloye Ojumu pẹlu nlọ dēdē.

Anfani nlanla nipe awọn Oyinbo Atawe wa mọ ilẹ lati kọ ile fun titu iwe nibẹ ni oṣu ti o kọja yi. Anfani nla si ni eyi, ki Ọlọrun ran alafia rẹ si ilu yi Amin.

O tun tasi wa leti pe D.O. Ifọn yio tete wa si Ọwọ lati ma gbe ibẹ, a bẹ ẹnyin ẹniti nto Kristi lẹhin ki ẹ gbadura fun alafia Ilu Ọwọ.

Anu se ni lati ma gbọ pe awọn kan a mā pe ara wọn ni "Alalumagere" nigbagbogbo ni wọn a mā ba alafia ilu arẹwa yi jẹ; nigbati wọn ba lọ si ile onile wọn a pa irọ tan wọn jẹ wọn a si ko inkan onile lọ.

Ki Ọlọrun fi awọn ti ṣe iru iṣẹ yi hàn o, ti wọn si ba ilu daradara yi jẹ mọ ni lọwọ. F. Ọwọ.

---

## EKITI KO SI LABẸ ILẸṢA.

Mo yin ẹnyin ọmọ Ijẹṣa pupọ, nitori pe, ẹ ngbe Ọwa Ilẹṣa Ọba nyin ga gidi-gidi: E nbuyi fun u pupọ, o dara bẹ, ẹ ṣeun jọjọ. Ki Ọlọrun ki o jẹ ki ilu nyin na ki o ma dara si i titi. Ki O maṣe jẹ ki a tun ri ohun ti yio ba a jẹ mọ.

Ọpẹ nla ni fun Ọlọrun nitori anu Rẹ ti o se iru iyipada nla bayi ti gbogbo awa ti a ti jẹ ẹru ri fi di ominira. A si tun le mã dupẹ lọwọ Ijọba Gesi ti o fi se ohun elo ãnu na ki a si ma gbadura fun wọn.

Ọrọ otitọ ti o daju ti mo fẹ fihan ninu iwe yi ni pe, Ekiti ko si labẹ Ilesa rara. Iwe na si tọ si mi pupọ lati kọ nitori emi li o ku li agba ọmọ Ekiti loni. Awọn aṣaju mi ninu igbagbọ ti o le kọwe silẹ fun iran ti mbọ ti lọ si ibi ti agba nre.

Awọn ti o tilẹ sãju mi na ko pọ tobẹ; ng ko mọ ju awọn mẹta pataki Daddy V. Agbebiyi Ọmọ Arigidi, Daddy T. Faoye ọmọ Isẹ, Mammy Doherty ti Josiah Doherty ọmọ rẹ fun ilu iya rẹ li ẹgba pọnun; nitorina iwe yi tọ si mi ni kikọ pupọ. Ẹniti o mọ ire ni sise ti ko se e ẹsẹ ni. Nko si le sai kọ o silẹ fun iran ti mbọ. Mo si ni ireti pe, Ọlọrun yio lo iwe yi fun ire Ekiti lọnakọna, ohunkohun ti Ọlọrun ko ba se, o daju ko si ẹni ti o le se e.

Ọlorun ko fi Ekiti si abẹ Ilesa, ko le se ise, asoro se bi ohun ti Ọlọrun ko se. O da mi loju pe Ọlọrun ki ise ibi; ki yio fi Ekiti si abẹ Ilesa lailai gẹgẹbi ifẹ awọn ọmọ Ilesa.

Awa ati awọn li ogun jọ ko lọ nitori aimọ Ẹlẹda wa ti a jọ lọ se ẹru; Ọlọrun jẹ Alanu ati olõtọ, ko jẹ tun jẹ Ekiti ni iya lati tun tẹ wa mọlẹ si abẹ wọn nigbati a ko ti si labẹ wọn tẹlẹ ri. Eyi na ni a nma wipe ki Ọlọrun ki o ma jẹ ki agba ki o tan lori ilẹ.

Ọmọ Ekiti na sa ni Daddy Agbebiyi ti o kọ wa si Ilesa lati ọdọ C.M.S. lati wa fi ọrọ Ọlọrun kọ awọn Ijesa, oun li o kọ fi A.B.D., kọni ni Ilesa. E ha ti se? ti ẹ o wa mọ iwe tan, ti ẹ o wa fi iwe jẹ ọmọ Ekiti ni iya, ti ẹ o fi ọgbọn iwe sọ wa di iransẹ nyin? O da mi loju, ọmọ Ekiti ti o kọ wa si ọdọ nyin ko jẹ nyin ni iya emi mọ eyi daju nitori o ni ẹru Ọlọrun. O rohin fun mi iru iponju ti o ri ni ilu nyin.

Ọmọ Ekiti fi ọrọ Ọlọrun kọ nyin o fi ọmọbirin rẹ fun nyin, o ku si ilu nyin, oun jẹ ẹniti o bẹrẹ ọgbọn iwe ni ilu nyin. E ma se fi ọgbọn iwe sọ Ekiti di iransẹ Ọba nyin o, ko dara bẹ, ko si le se se. Bi gbogbo iran yi ba ku tan, iwe ki sa ku. Gbogbo ẹniti o ba nka awọn iwe ti ẹ kọ, ti ẹ nwipe Ekiti wa labẹ Ọba nyin ki yio le si iyan jija si ọrọ na mọ. Bi Ijọba Gesi ti o jẹ Ijọba olõtọ ti ki se ẹgbe, ti nwọn si ntẹle otitọ, ti gbogbo wa wa labẹ wọn ba fẹ, nwọn tun le wadi inkan na daju lakoko yi. O daju pupọ, Ekiti ko si labẹ Ọwa Ilesa rara. Ti pe, oun li olori alade, ọrọ lasan, awọn ọmọ ilu rẹ li o nfi ọrọ na gbe e ga, ko ri bẹ rara.

Awọn ọrọ ti o fi daju gbangba pe Ekiti ko si labẹ Ọwa Ilesa ti a o sọ li ẹ o rika nihin yi.

Ajimọkọ Ọwa Ilesa wa ilọsiwaju ilu rẹ pupọ. Oun li o kọ bẹrẹ si wa ọna ọgbọn lati tẹri Ekiti ba si abẹ Ilesa. Ewi Ajimuda-ọrọ ko si gba. Nijọ kan o kọwe si Ewi na bayi pe, Oyibo wi fun oun pe, ki awọn jọ wa enia ti yio ba Ijọba Gesi lọ si ogun, o fi iwe na ran Eleyinrepo. Ewi ransẹ pe wa lati ka iwe na fun u.

Nigbati Eni-ọwọ Ṣowumi kawe na fun u, o binu gidigidi, o ni bi oyibo ba nfẹ bere ohunkohun lọwọ oun ko le ran a si oun, yio ransẹ tara si oun ni, oun ki se ẹgbẹ rẹ. Ibinu na pọ tobẹ ti a fi ntu u ninu ti a nwi fun u pe, ki o mase fi ibinu se inkan nã. Emi ko le mã kọ gbogbo ọrọ ibinu ti o fi ran Eleyinrepo onisẹ rẹ si i, o tẹnu mọ pe oun ki ise ẹgbẹ rẹ pupọ, o si sọ fun u pe, ki o jisẹ gbogbo ọrọ ibinu na fun u bi o ba de ile. O tun wi ni ibinu pe, oun ki ise ẹgbẹ rẹ ki o mase tun ran iru isẹ bẹ si oun lailai. Eni-ọwọ Ṣowumi fun u ni imọran pe, ki o fi pẹlẹpẹlẹ kọwe dahun iwe ti Ọwa kọ si i. A ko tun ri onisẹ kan lati ọdọ rẹ tabi lati ọdọ Oyibo ki o wa bere pe nitori kini Ewi se binu si i bẹ, ti o si sọ ọrọ aidara pupọ bẹ si i.

*Koi ti pari.*